# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. II. No. 84. SATURDAY, FEB. 16, 1924. Fourpence.



## DURO THOMAS.

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

**"Specialities: Enamelware, Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails Rangoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano, Padlocks, Beads, etc., etc., etc."**

---

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

**J. F. SICK** ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode Iailai, l'eti *Glover Memorial Hall, (Customs Street,)* EKO.





Awọn Oyinbo Onisowo yi nranṣẹ Masini-Aranso ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati ṣe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranṣẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu Masini na.

Awọn Oyinbo yi nṣe oriṣiriṣi Ilẹkẹ alarakara, nwọn si nranṣẹ *Cement* ati panu kikọle to nipọn, ati eja abọmalọ ati oriṣiriṣi ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi si nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ Asiri nipa Owo. Irohin ko to afojuba.

## J. C. VAUGHAN

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "Excelsior" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun ẹkọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awon onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ o.

## B. O. Joseph

*Commission Agent.*

21 years experience in trade.

**Cotton.**

**Sundries.**

**Hardware.**

**Provisions.**

27, Koseh Street, Lagos.

Cable Address:— "Steinafrik" HAMBURG.

## E. H. STEIN & Co.

HAMBURG, Neurwall 16/18, Hildebrandhaus.

*AFRICAN MERCHANTS.*

***ALL INDENTS EXECUTED.***

for

English and Continental Goods

and

PRODUCE

Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**

*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos :—

**Mr. Karimu Kotun**

Broad Street, & Portonovo Market Store.

## FOR SALE.

One secondhand Harmonium with 4 Octaves.

*Price Moderate.*

Apply to Mr. A. ONIORISAN c/o P. Z. Lagos.

## BULL WEST AFRICAN LINE, INC.

AWỌN ỌLỌKỌ TI IJỌBA AMẸRIKA

Ọkọ elefi awọn Oyinbo wọnyi nko ero ati ẹru ni Iwọ Orun Afrika, ni oşoşu o si ngba ero lọ si ilu Amẹrika ati awọn ilu miran pẹlu. Ọkọ wọn yara, owo pọ ni nwọn si ngba. Ẹnyin ero, ẹnyin onişowo Obi, Koko, Ekurọ ati Epo, ẹ lọ ke si aşoju awọn Ọlọkọ yi ni :— Oke Pẹtẹsi ile *Colonial Bank*, ni Ẹhin Igbẹti, Eko.

## ERO YA WA RA.

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" ni Panu-kikọle ati kikan-ọkọ, Iṣo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun-ẹrọ, ati Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa l'okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Ile-ọja rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

OWO ỌJA RẸ FANIMỌRA.

Ẹ LỌ RA TIYIN NIBẸ.

*Editor & Proprietor* :—
ADEOYE DENIGA,
*Offices*: 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

———:o:———

### ȘI FILA, ȘI FILA, A KO FI T'ỌMỌ AWO ȘE !!!

Ninu Kōtu awọn *Jury* ti a ṣe kọja l'oṣu yi, Dẹrẹba kan fi aṣọ Ọba jaba nipa hihu ọmọdebinrin kan ni iwọsi ni Ikoyi. Ṣiwaju ki ọdẹlẹsinrin yi to hu iwa aja yi, o nfi owo kọrẹnsi pupa oni poun kan niwaju ọmọ na lọgan bẹni Dẹrẹba yi si paṣẹ fun awọn Ẹlẹwọn meji ki nwọn mu dani fun on, titi so-ndoko yi fi tẹ ifẹ ara rẹ lọrun ; bi o si ti pari iṣẹ rẹ tan, bẹni Ofin Amunimuye (*Criminal Code*) fi làkàlàkà ; agbaregbabọ rẹ ni pe Dẹrẹba ọ̀bàyéjẹ yi jẹbi ẹsun ti a fi sun, Adajọ Agba si ju si ẹwọn ọdun marun pẹlu iṣẹ aṣegan, a si bu bilala mejila ti a o fi bo o ni idi fun l'ọgba ẹwọn.

A gbọ pe ọja ni ọmọdebinrin yi nkiri ki o to lọ ṣagbako Arigidenia yi lọna Ikoyi. Ẹnyin Obi ati Alagbatọ ọmọ ti ẹ ngbe ọja le'ri ọmọ nyin fun kikiri, agba d'ọwọ nyin o, ẹ ko r'aiye lode. Dẹrẹba yi ro pe on le fi aṣọ Ọba *King* ti o wọ ṣe bi o ti wũ ṣugbọn ofin Amunimuye ti oju rẹ yọ'da, o ti ẹhin rẹ kĩ si.

### ARA, EKO, Ẹ KO NRỌWỌ GBẸNA LARA IGI ?

Igbimọ Aṣofin ti *Nigeria* bẹrẹ ni *Monday* ọsẹ yi, gẹgẹ bi a ti kede rẹ ṣiwaju : gbogbo ẹsẹ awọn Ọlọla wa lo pe s'ajọ t'Ọba ti Ijoye. Ibere ti awọn mẹta Aṣoju Ilu Eko pẹlu ti awọn Aṣoju Ilu miran t'Oyinbo t' Enia Dudu to ọlọlã du loye. Ọlọla Dokita Adeniyi Jones sọ pamọleti ọrọ ninu Igbimọ pe ki Ijọba tun ṣi Ile Elegbo ti Ereko fun awọ Mẹkunnu ati awọn enia gbogbo. Ọlọl Eric O. Moore gbẽ lẹṣẹ, gbogbo awọ enia wa to jẹ dudu to wa nibẹ lo jẹ ọhẹ si ọrọ yi ; a si dupẹ lọwọ Oyinbo Aṣoj òwò ti Kano fun fifi ohun ṣọkan pẹ awọn ara wa ninu ọrọ yi nigbati o j pe gbogbo awọn Oyinbo ẹgbẹ rẹ toku lo ṣ'agunla si imọran na, nigbati a si ka iye awọn ti nwọn ni nwọn fẹ ki a ṣi Ile Elegbo na, nwọn jẹ 8 ; iye awọn ti nwọn ni nwọn ko fẹ ki Ijọba tun ṣi mọ jẹ 21 iyẹn ni pe ọrọ na ṣi boti las'ko yi ; ṣugbọ inu wa dun nigbati a ri Ọlọla Oloy Donald Cameron to dide to si gba Ọlọla Dokita Jones niyanju pe o le tun mu ọrọ rẹ na wa si Igbimọ nigbati o ba ṣe.

Inu wa dun nigbati a ri diẹ ninu awọn Oloye wa Oluwa ati Olorogun ti nwọn wa s Igbimọ yi ati Ọgbẹni Braimah Igbo laik ọgọrọ awọn oniṣokoto-gbọrọ miran nibẹ a si ri Bishop Howells nibẹ pẹlu.

### ẸNYIN ỌMỌGE ATI IYA AFIN, ISE MBẸ BI ABA.

Ori ṣi ni nigbati a ri Ọlọ'a Ọmọ Ala K. Ati Amonu Aṣoju *Calabar* to d lati bere lọwọ Ijọba ni Igbimọ yi *Monday* kanna bi aye le wa fun a obinrin ti nwọn ni ifẹ lati ṣiṣẹ labẹ Ọba papa awọn obinrin ti o laju ni *Calabar*. Ọgafa Ọlọla Sẹkitẹri pataki ti Ijọba Sir Donald Cameron si fesi pe Ijọba npete ati gba awọn obinrin si Iṣẹ Ọba fun iṣẹ Iwe-riran (*Women Book Binders*) ọrọ re o, ẹnyin "*Member*" ki a ri ninu nyin ti o ma lọ gba iṣẹ yi o nigbati o ba ṣi siṣẹ ; nitori oye to wa ni ki a ṣiṣẹ Ọba tabi iṣẹ miran ko kere. Nisinsinyi a ẹọ nri awon Iya-afin l'eni tere, eji tere, ti nwọn lọ ṣiṣẹ ni ti awọn Oyinbo Oniṣowo

o ba dabi irọ, Atampako la fi njuwe kankan, Ẹ lọ bẹ Ile Ọja Meremere awọn gyinbo *Lever* ti a ṣeṣẹ ṣi ni lọlọyi ni popo-nla wò. Majẹ 'a gbọ irọ lo njẹ bẹ̀!

### ỌDUN MARUN ỌJỌ GBỌRỌ.

Irohin kan ni lati Abẹokuta wa pe A ì ẹnikan to njẹ Majẹkodunmi s'ẹwọn ọdun narun fun ẹṣẹ dida-owo-ṣile-ṣe.

Lọwọ gbogbo Isare Ọla ōjọ̀—Oluwa rere gba wa !!!

### KERE O! KERE O!!

Ọdomọkonrin ọmọ Ijẹbu kan ti o njẹ Michael Ẹkundayọ Paṣeda, ti o ti kuro nibi iṣẹ wa, nlọ lati ile de ile awọn agbawe (*Subscribers*) wa; o si nfi orukọ wa gba owo "*Eko Akete*" nipa sisọ pe owo-asansilẹ wọn tan, laijẹ pe a ran niṣẹ. A kilọ fun ẹnyin ọrẹ wa ti ẹ ngba Iwe-irohin yi ki ẹ maṣe fun ọkọnrin na ni aiyelujara ọlọgbọnwo nigbati o ba de ọdọ nyin fun irufẹ ọgbọn jamba bayi. A ko ni nkankan pẹlu rẹ mọ.

Akọwe wa ti nṣiṣẹ yi ni *Pass Book* wa lọwọ, Ẹri wa si leyi.

### ABIAMỌ KUṢẸ

A ba Iya Afin (*Mrs*) Haffner ti Ita Haffner kẹdun ti Igbi aiye to la lọsẹ yi nipa ọkan ninu awọn ọmọ rẹ ọkunrin Fred ti o ti nṣe Alagbẹdẹ Wura ri, ti a fi s'ẹwọn ẹṣu mejila pẹlu iṣẹ aṣegan lọsẹ yi ninu Kotu awọn *Jury* nipa Ẹsùn ti a fi sùn pe o dabaru Akọnta ọja ti o ta bi Akọwe awọn Oyinbo *G. B.* ni Ṣabu wọn l'ẹhin-Ọgba.

### AJA LO L'ẸRU, IRỌ NI PẸPẸ NPA.

Lọwọlọwọ yi, Igbimọ Aṣofin *Nigeria* ṣi mba lọ, ibiti nwọn de nisinsinyi ni ti yiyẹ gbogbo awo ti Ijọba yio na fun iṣẹ Ilu fun ọdun *1924—1925* wo finifini. Iṣẹ awọn Ọlọla Igbimọ na kuro lawada.

### Ẹ KU ṢẸ.

A sọpẹ lọwọ Ọgbẹni I. J. Oluwole Ṣoyọde fun Iwe Almanack rẹ ti ọjọ ọja to fi jin wa lọsẹyi. A nta iwe na ni tọrọtọrọ lọdọ Oni'we-irohin "Eleti-Ọfẹ" ni Ita Victoria.

### ABỌ O.

A ba Ọgbẹni *Akinyẹmi Amosu ti Ita* Ondo, Ebute Mẹta yọ fun ọmọbinrin titun kan Adukẹ, *ti* aya rẹ fi ta lọrẹ lọsẹ to kọja.

## FACTS AND FIGURES

### MUNICIPAL MEASURES' FATALITY.

#### A great Peril.

That a law should be passed making it an offence to sit on any of the elevated pavements of some of the large drains in Lagos or Policemen be engaged to keep people off sitting on them is within legitimate ways and methods of an institution, such as the municipality, that purports to stand for the welfare of the people. But that institution ceases to act in keeping with the fundamental principles upon which it is founded the moment it adopts measures which are apt to spell detrimental—or do grevious bodily harm—to the very people for whose welfare it is founded when such measures could be easily avoided.

In the first place it would be well to remember that in tropical countries, unlike Great Britain and other European countries, people take much delight and pleasure in sitting outside on pavements and other seats available in the street thereby releasing themselves of the great heat they have unavoidably suffered indoors all the day and West Africans cannot but view with great horror the monstrous appearance of the pavements in question firmly set with long, thick and sharp-edged nails apparently to prevent people from sitting on them.

This may be wise in broad daylight; but it is in the night that it does its harm. Lagos is a place where a percentage of its population does not move about in the day time and naturally in the evening people are seen strolling about evidently "taking breeze." They stroll about some quarters otherwise engaged in the daytime with traffic and such people sometimes feel tired and intend to take some rest on the nearest seats or pavements (there being no special public seats) and then !!!

There are several cases in which unfortunate individuals had been mortally or greaviously wounded. For the present we shall give only three instances which happened within a very brief interval.

A few months ago a man was reported dead of wounds received from innocently sitting on one of these pavements. The incident was reported in local papers including this paper and "Eleti Ofe" at the time.

One evening, two months ago, the writer was passing through Customs Street and saw a little crowd gazing at a violent man who was engaged in a struggle with the Policemen. An order was given by a Sergeant to disperse the crowd and in a rush a youngman was elbowed and fell heavily on these sharp nails—the wound was terrible.

The third instance is that of a young lad named Taiwo Williams who by the time this paper is being read, is under the medical treatment of Dr. Obasa of Ikija.

This lad while playing had fallen a victim to these sharp-edged nails. A report of this incident appeared, under the Caption "A ko le gbe'le gb'ofa lai r'ogun," in the last issue but one of "Eleti-Ofe" as follows:—

> Anu abiyamọ ṣe enia lati ri ọdọmọde kekere kan ti a npe ni Taiwo Williams ni *Friday* ọsẹ ti o kọja nigbati o fi ara nla pa nibi *gutter* ti a kan iṣo mọ lori, ti awọn Ijọba ṣe siwaju ile ọja awọn Oyinbo "African Association" ti Davies Street; bi o ba jẹ wipe awọn Ijọba kọ fẹ ki awọn enia ma joko le ori *gutter* yi ni nwọn ṣe kan iṣọ mọ lori, yio dara pupọ bi nwọn ba le fi ọlọpa sibẹ lati ma kilọ fun

bọ'ju lararọ dipo omi ni, aṣiwere ni ẹ. Bi ẹniti o fẹ fi agbara ifẹ rẹ tẹ ori gbogbo enia ba lo jẹ, iwọ gan ni olori aṣiwere. Ẹnikẹni to ba ni iru alebu ti a ka silẹ yi, buru loju wa ju aṣiwere Yaba lo.

Ofin ki a ma fi orukọ silẹ lọdọdun bayi nitori a ti le yan Aṣoju nigbati akoko ba de, a koi ni ti sọ bi o dara, tabi ko dara titi di ojọ miran, ojọ rere, ṣugbọn imọran ti a o gba Ilu nisisiyi ni pe ki nwọn maṣe jafara ati fi orukọ silẹ.

Ẹ dide, ẹ dide, sari to.

Emi ni tiyin nitotọ,
ATARI AJANAKU.

---

### FROM THE EDITOR'S SANCTUM

OUR AUTHOR-PRINCE.

"History of Abeokuta" by Prince J. B. Ogunjumi Losi. Copies of this publication are on sale at the C.M.S. Bookshop Price 1/6 each. The book is evidently a *Multum in Parvo*—It is a treat to read it.

---

### THE RETIREMENT ON PENSION OF
## F. G. V. Macaulay, Esq
*Of the African Direct Telegraph Co., Ltd. Lagos.*

To The Editor, *Eko Akete*.

Please allow me a space in your valuable Journal for the following :—

I was aware that F. G. V. Macaulay Esq., of *The A.D.T.C. Ltd.* Lagos retired on pension as from the 1st October 1924, after his 34 years, faithful service as a Telegraph Operator and Superintendent a[illegible] local Cable Office Lagos. And to him hon[illegible]hly due and without the fear of any c[illegible] I assert that Mr. Macaulay is a we[illegible]nd bred gentleman throughout the [illegible]ners of this country. I need mention [illegible] a very short period of time that I had the opportunity to be under him as a Telegraph Learner in the year 1912. I found him to be a thorough and perfect gentleman. Before Mr. Macauley leaves his office (The Cable Office) he has laid a very good example for other young folks there with him and not only that he has also left them with words of encouragement which no doubt will induce those who are still in the Cable Boys Field to learn how to endure circumstance in life. He also lives thus :—Be a fool to be wise. A patient dog eats a fat bone. Mr. Macaulay had been a fool but yet he is wise he has been very patient and now he is sucking his fat bone. I congratulate him from my heart of hearts for having waited patiently untill he is considered worthy of pension by the Authorities of The Cable Company both in Lagos and in Europe.

May God spare his life for many more years to come and enable him to enjoy his pension with ease and happiness. And to his family I extend my heartiest congratulations. Before running to a close I may remark as an experienced Telegraph Operator that (Mr. Macaulay) having served for *34 years* on the Telegraph Instrument his nerves would no doubt require a very long rest and to himself, he needs a great change, fresh and cool air, and I hope he would not feel quite uneasy for now being on no active service.

I for one as a youngman learn to be slow and sure in all my undertakings.

To crown all, I wish him again long life and many more happy days in future.

Sincerely yours
E. T. AKINSANYA NELSON DOMINGO DANIEL.

---

### ADVANCE, EREKO CHURCH!

The Wesleyan Ereko Church after thorough renovation was reopened on Saturday the 4th inst. at 4 p.m. the new brass communion rail was dedicated to Almighty God. It was bought by the Afunrugbin Society. All the Ministers took part. The Sermon was preached by the Rev. A. N. Cole Supt. of the Circuit.

---

### IGBẸ L' OWO WÀ.

### EKO.

Bi òwò Ekurọ, Epo ati *Cocoa* ti ku] si lọsẹ yi leyi :—

EKURỌ

£15 0 0—£16 fun *ton* kan

EPO.

£25 0 0—£26 fun *ton* kan.

COCOA.

£16 10 0—£20 0 0 fun *ton* kan.

---

**Bargain in Buying.**

One Second-hand Motor Cycle

**"Sunbeam"**

*As good as new; all parts complete.*

For sale; apply to the EDITOR.



**Kruschen Salts. 2/9 a Bottle containing 96 doses.**

### HE SINGS IN HIS BATH.

Hard things have been said about the man who sings in his bath, disturbing other people's sleep, but please understand his feelings he is singing out of the pure joy of his heart. He gets up feeling brimful of health and energy, he's glad to be alive, he welcomes the advent of another day of glorious existence, he offers up a song of praise—even though it's only a music hall song—having been born in such a wonderful world.

Well, that's something to make a song about, ins't it—you who grumble at his musical efforts—you would make music too if you got up feeling as he feels.

And you will feel that way—just bursting with the need of expressing sheer joy of living—if you take your dose of Kruschen Salt.

The little dose that does so much.

Just sufficient to cover a 6d. piece, tasteless in your breakfast cup of Tea or Coffee.

It will keep your kidneys and liver in order, it will remove all waste matter clogging the system, purifying and refreshing the blood, make you tingle in every fibre with new health, new vigour, new joy.

*Obtainable from all Stores and Chemists. Sole importing Agents for Nigeria* : B. ANDERSSON & CO. LTD., *P.O. Box 145, Lagos.*

**Springs! Springs!! Gramophone Springs!!!**

ALSO

**Isolated Bottles; Vaccum Flasks.**

Messrs. Remi Macarthy & Sons, of 5, Taiwo Street, Lagos, has just received a consignment of Springs adapted either for English or German Gramophones. Also (Thermos Bottle) Vaccum Flasks to keep water hot for 24 hours. The Springs and Flasks are sold at very moderate prices. Come and pick yours ere the Stock exhausted The Flasks are assorted sizes and bodies.

AWỌN OKUN-ẸRỌ TI GRAMOPHONE FI NKỌRIN, ATI IGO IFI OMI GBIGBONA SI

(T'omi ko ni fi tutu gba wakati mẹrinlelogun).

Awọn Rẹmi Macarthy *and Sons* ti nwọn ngbe 5, Taiwo *Street*, l'Eko ni awọn Okun-Ẹrọ ti *Gramophone* fi nkọrin lọwọ fun tita. Nwọn ṣẹṣẹ ri wọn gba lati Ilu Oyinbo, enia le lo wọn fun Ẹrọ *Gramophone* yala ti Gẹsi tabi ti Jamani. Wọn tun ni Igo ti a le fi omi gbigbona si gba wakati mẹrinlelogun. Owo pọ ọ ni wọn nta nkan wọnyi (Igo omi gbigbona fun tita wa) sure tete ki o wa ra tirẹ ki ẹran rẹ ma ba bi obukọ.

## J. C. VAUGHAN

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorișirisi lati adota ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onișowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ o.

---

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ṢOLANKẸ Onișowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikanọkọ, Iṣọ lorișirisi, Kọkọrọ (Iṣika) t'ilẹkun ati t'apoti lorișirisi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorișirisi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọṣan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorișirisi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-ṣawa Pokun ati Ẹja Abọmafọ, ni Ṣọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (I'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (I'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-iṣẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ

On si ni aṣoju awọn ẹgbẹ Oyinbo onișowo to njẹ Arnold Whitehead Ltd. to wa n Manchester [illegible] yinbo) to si nranṣẹ orisi-riṣi ọ[illegible] ọdọ wọn ni Eko ati agbegbe rẹ [illegible]ere ẹhin ọrọ nipa owo yi lọwọ rẹ [illegible] rẹ tabi ki o kọwe ranṣẹ si ki o fi ṣ[illegible]inu apoti ikọwe si t'Ọba P.O. Box No. 796, Eko, Nigeria.

---

### Coffins to suit your Taste.

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at A. Kessler's Establishment, 7, Labinjo Lane, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

## Sabu Ajisefinni.

Gbakan-nṣubu orișirisi Ọti *Boer* to jẹrẹ wa fun tita ni Ṣabu Ibukun Oluwa, Ṣabu ti Mrs. A. Labinjọ ni No. 28, *Luther Street*, leti Mọṣalaṣi Olosun. Sarotu kẹkẹkẹ (*Cigarettes*) si nbẹ nibẹ bi tẹdi. Awọn *Lozenges* ati *Peppermint* lila, papa lakoko oworẹ yi ko ṣe fọwọrọ sẹhin. Gbogbo awọn ọja Ṣabu na lo nẹẹju si ni, pe kami, kami, kami.

Ọrẹ, sure tete lọ ra tirẹ nibẹ.

Kai! afara ni'ja Ẹkun.

---

Cable Address:—
"Steinafrik" HAMBURG

**E. H. STEIN & Co.**

HAMBURG, Neurwall 16/18,
Hildebrandhaus.
*AFRICAN MERCHANTS.*

*ALL INDENTS EXECUTED.*
for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.
*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos:—
**Mr. Karimu Kotun**
3, DOSUNMU STREET.

---

**Ruby Plates! Ruby Plates!!**
**Ruby Plates!!!**

BOON TO GOLDSMITHS

*Just arrived.*

Call at once and make your choice from:—

DURO THOMAS,
55, Massey Street, Lagos.




*Reduced 3/- each.*

ACCESSORY AND PARTS

**For Bicycles For Motors For Gramophones.**

ASK FROM

KADUNA STORES.

79, and 81, Odunfa Street, Lagos

*Near the palatial building of the late Mr. A. W. Thomas.*

And also expert in repairing all.

S. ADE CLAY.

---

Ọgbẹni T. A. Ẹrinoṣo jẹ Ojulowo Oniṣowo. O nfi ọja ranṣẹ, o nta ọja, o si nra ọja, o jẹ Oniṣowo pataki ninu Ekurọ Epo, ati orisirisi Ọja miran. Ọgbẹni na si tun jẹ ẹniti o gba iwe ati ma ta Ilẹ, Ile tabi Oko.

Ẹ lọ fi Ọja nyin fun u ni:—

19, Opopo Tinubu,

Tabi ki ẹ kowe si ni:—P.O. Box 242, Eko.

---

## T. A. Erinosho,

*Forwarding Shipping, Buying, Selling and Commission Agent, Land and Estate Agent, Produce Merchant Licensed Auctioneer & Valuer.*

19, Tinubu Street, P.O. Box, 242, Lagos, Nigeria.

---

## JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos, at

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*

---

ILU EPE KO KERE L'AWO. ẸIYẸ O BA LO GE.

Ọgbẹni S. A. Q. Macaulay ti No. 88 Opopo nla l'Eko nibi ṣẹṣẹ ṣi Ile Egbogi to kẹriri kan si eti Ebute l'Ẹpẹ.

Ile Egbogi na ko jina si Ile-Ọja awọn Oyinbo Oniṣowo John Holt.

Ọgbẹni yi ni Ajẹlolẹru Egbogi ni Ṣabu na, eyiti ki foju arunkarun ba'lẹ gẹre ti a ba ti lo wọn.

Ẹ wa dan a wo: bẹ lẹ o ba.

Ọpọku-ọyọku ni owo tita wọn.

---

B. A. ỌLA SILVA,

**Certificated Typewriter Mechanic**

*5 years Mechanical experience Marine Work Shops.*

Undertakes Repairs of Typewriters, &c., at moderate charges.

*Business Place:*

30, DOHERTY STREET, LAGOS.

**A Trial Solicited.**

---

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay,

88, BROAD STREET.

Wabiwọsi orisirisi Egbogi lo ṣẹṣẹ de fun wa ni tita: awọn bi:—ogun Egbo orisirisi, ogun Ẹda, ogun arun aṣiri, ogun Arẹmọ, ogun Onigbameji, ogun Aran orisirisi, ogun Lakuregbe, ati awọn ogun miran ti a ko lẹ mã to lẹsẹsẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo wọn, nwọn si jẹ bi idan.

Ọrẹ, ẹ lọ dan awọn Ogun wọnyi wo nitu ti a gbe nta wọn.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.